# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 109. SATURDAY, AUG. 16, 1924. Fourpence.


## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

13 AUG 1924 LAGOS

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orișirișị Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubbẹr, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elẹjo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Olokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumădan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọny fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Așọ Aran, Ẹrọ agbado, Ile, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipanu, așọ iș'ọșọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọșọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Mașini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# John Walkden & Co. Ltd.

SUNDRIES DEPT.

MARINA, LAGOS.

## We recommend you to try our :—

"Elephant" Beer

Ginger Ale

Lemonade

Red Buffalo Gin

Black Prince Gin

Gilbeys Gin

Old Tom Gin

## QUALITY THE BEST.

ALL PRICES REDUCED.

**we hold a large stock of various Sundry Goods at cheap prices.**

*Editor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa, 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

ARA MA KỌ ṢU O ṢU INA! EYI TI JẸ? DỌKITA LA MỌMA-TO-NM'EGBO-OJUGUN. ESỌ RẸ O!!!

Ikunsinu ni ilu pọ rekọja ala fun iwa bibẹ-to-tọrọ-akọde ti a gbọ pe ọdọ Dokita kan ti o jẹ Enia Dudu bi awa papa, ti o ṣẹṣẹ ti Abẹokuta wa si'lẹ yi, ti a si gba sibi Iṣẹ Ọba ni Ọgba awọn Munisipa (*Sanitary*) hu ninu ọsẹ tokọja ti o fi d'ogun pe lila lo tọ si oku Dokita Beckley to ṣ'alaisi ni ọsẹ tokọja; bi eyi ba ri bẹ, njẹ imọran ti a le gba irufẹ Dokita yi nipe Ọrẹ ni a wa kun ọrẹ, koyẹ ki a wa ọta kun ọta.

KINLA, OKU LANGBODO LỌ KA A.B.C. NI ṢUKURU?

KILA TI PIN 'TAN AJA KO TO KAN LEMỌMU?

Ganku ti awọn enia diẹ ni kutukutu hai arọ Satide tokọja kan oku ti o ti ku lati Ile Alarun wa ti a si tẹ si Ile Iwe *St. Peter*, mu ni bere pe kini ba eyi wa? A sọ pe ẹniti o ku na ko ni iyekan ati pe "*Member*" Ṣọṣi na ni, ati pe boya nitorina lo ṣe di pe a ntẹ oku rẹ si ile-iwe awọn ọmọde; bi eyi ba ri bẹ, ko wọ rara; kini apo ọkun ti ṣe di Akala si ọmọ titun? A ko ro pe Ile Iwe ọmọde lo yẹ ki iru eyi ṣẹlẹ; a ni ireti pe boya Alufa ibẹ yio la wa loye eredi ohun ti a gbọ yi, lẹhin igbati a ba ti tọka rẹ si ọrọ ti a sọ yi.

GASA, ỌJỌ NRE 'BI ANA!!!

Ṣaṣa enia ninu wa lo ma ranti pe ọjọ *Friday* Jimọ ọsẹ tokọja lo di ọdun Karun gbako ti Gomina wa, Gomina Clifford pẹlu iyawo rẹ ti de si ilẹ yi gẹgẹbi Gomina *Nigeria*; ni gasikiya, ọjọ ki pẹ.

*EPISTLE* KEJI TI "ATARI AJANAKU" SI AWỌN ALAREDE.

L' ọsẹ to kọja, a tẹ *Epistle* kinni ti *Atari Ajanaku* si awọn alarede, sinu iwe irohin wa, a si tẹ *Epistle* keji sinu ti ọsẹ yi. Oyin mọmọ ni awọn mejeji, nwọn kun fun ọrọ iṣiri ati ilaju, ati ofin arede!

Ara, ẹnyin ha ti ri ka bi? Ijafara l'ewu.

IKU NBẸ, ALUMỌTU!

Tẹdun tẹdun ni a fi tu ọfọ iku ọdọmọkunrin Dr. E. Olubomi Beckley, M.B. ati bẹ lọ ti o ṣẹlẹ ni Satide ọsẹ to kọja, ki Ọlorun fi si afẹfẹ rere, ki o si tu awọn enia rẹ ninu.

*Atari Ajanaku* ngb'ero lati sọ fun ẹnyin ọkawe wa diẹ nipa inu rere oloye nla yi, diẹ nipa ajọ ati itara *Dr.* Macaulay ti o tọju rẹ ati diẹ nipa *Dr.* I. Ladipọ Oluwọle.

ỌBA LO T'EHIN ERIN FỌN.

Wiwolulẹ lo pẹkun awọn ile diẹ to wa lapakan oju irin l'oju Oto (*Massey Street*) ti ọna jẹ, lẹhin igbati Ijọba ti sanwo to jọju fun awọn onile na tan; ẹniti o ba gba ibẹ lati *Monday* ọsẹ yi, yio ri bi iṣẹ ti npe iṣẹ ranṣẹ.

Bẹ si ni a tun ri i ka ninu Iwe-irohin Ijọba (*Government Gazette*) ni lọlọyi pe Ijọba tun fẹ gba awọn ile diẹ ni Ile Elegbo-Turuku to wa ni Ita Ẹlẹiyẹ fun fifẹ Ile-Elegbo na, ati fun kikọ ibiti a o ma tọju awọn obinrin to ba ṣẹṣẹ bi majẹṣi.

Eyi wu wa o!

IYA RE'LE O, ILE LO LỌ KO ṢINA!

A ba *Mammy* Ogunbiyi, awọn Iya Afin A. Labinjọ, D. Silva ati Ọgbẹni Mọmọdu Sanni ti *No.* 66, Ọbadina *Street*, 28, *Luther*

*Street* ati 39, *Glover Street* nibi, daro ọfọ to ṣẹ wọn ati awọn iyekan miran ni *Sunday* tokọja nipa *Mammy* Patience Taiwo Ogunbiyi to lọ sinmi l'aiya Jesu ni arọ *Sunday* na. Ẹ ku afẹku, ẹhin Iya a dara o!

Sisin ti a sin Iya dabi ẹni sin iyawo; nṣe ni Mammy ati awọn Iya Afin Angelina Labinjọ ati Damiana Silva nnawo bi ẹlẹda, ti onjẹ npe onjẹ ranṣẹ, nkan mimu nkọ kẹ; iyẹn ko ni'ṣọ; bẹna ni Ọgbẹni Mọmọdu Sanni ko kẹrẹ. Ẹ ku inawo ọjọ!

OṢE! O PỌ!! ỌNA KU, OHUN ỌWỌ RẸ GBE 'LẸ.

Ta lo le mọ pe awọn Oye ti *Dr.* Emanuel Olubomi Beckley to ṣ'alaisi l'ọsẹ tokọja gba tan leyi? Ẹ jare ẹ ba wa ka wọn:— M.A.; M.B., Ch.B., L.R.C.P., L.R.C.S., L.F.P., and S., D.T.M., and D.P.H.

Pagidari! Ẹkun ku a nf'ọwọ ba a!!!

ADURA FUN OHUN TO BA ṢORO, BABA YIO GBỌ ẸBẸ.

Awọn Ijọ Atẹnibọmi (*Baptist Church*) pero pọ lati ṣigun adura fun gbogbo ohun to de ba aiye lakoko yi.

Nwọn o bẹrẹ ni *Monday* ijọ kejidilogun titi di *Friday* ijọ kejilelogun oṣu *August* ni ago meje alẹ ni *First Baptist Church Broad Street.*

EWO NI TI OLE OJUKOJU?

Ni Satide to kọja obinrin afọju kan ni Ita Bamgboṣe fun ọkọnrin aganyin kan ni ọgọrun pọun (£100) ti o gba ni Kotu ti o jẹ tirẹ pamọ loju ẹlẹri di *Monday* ọsẹ yi. Nigbati ilẹ *Monday* si mọ, ti obinrin na lọ bere owo rẹ, bẹni agbalagba ọmọ jaguda yi bẹrẹ si ba obinrin na ro lọya pe *Receipt* ti on fun u da? Iyoku ira a, nwọn ti ra ọkọnrin yi mu, o di rẹrẹ lọdọ Baba Ẹgbẹ ni Ita Ẹfunroye (Ita Tinubu).

OPE-APE'RUN.

Ka tun gbọ pe a ṣi tun ri ninu awọn enia wa nidayi, ti oye koi ti ye nipa pipa'riwo alaimọkan fun ṣiṣẹlẹ ohun ti o ni lati ṣẹlẹ lakoko rẹ, ki o si rekọja; bayi la ri ni alẹ *Thursday* (Alamisi) ijẹta ti gbogbo ilu gb'ojikon, a ri awọn obinrin ati ọkọnrin ti nwọn ni nwọn nṣe waka ki orun ba le fi oṣupa silẹ; ẹ sa gbọ orin ọmọde ti nwọn nkọ na:—

Oṣupa pẹlu orun nja,
Fi silẹ o.

Awọn oloye mọ pe irufẹ pipade ti orun pẹlu oṣupa pade ara wọn lati iwọn agogo meje alẹ titi di agogo mọkanla oru ọjọ na jẹ ohun ti o ti han ninu Iwe Ika'jọ oṣu ọdun ni (*Calendar for 1924*) ki si ṣe ohun abami kan ti a ko ri ri; bẹni nwọn pade ni ọjọ kẹrin oṣu *July* ọdun *1917* ọhun, ti nwọn si tun yago fun ara wọn bakanna. *Eclipse* ni a npe irufẹ ipade bẹ.

A ro pe ẹ o fi opin si iwa alaimọkan ti ọpọlọpọ hu lalẹ ọjọ na, nipa kike kakiri bayi.

BABA BO BABA MỌ 'LẸ.

Ina to ṣẹlẹ lalẹ ijẹta ni gba-ngba Anikantamọ mu ọgọrọ aimọye enia wa sibẹ; ohun ti o panilẹrin ninu rẹ ni pe awọn ti o npariwo "Oṣupa ko le ja, la la la j'ọwọ rẹ" yara fẹ kito titi awọn Panapana fi wa gba ina na ti o ṣe jamba fun ile panu kan nitosi ibẹ ti obinrin kan ngbe, o si jo awọn ile ikin kekeke ti a kọ sibẹ raurau.

---

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE"

Nigbati aisan iya wa yi nle ni iwọn ijọ kẹta ki Ọlọrun to pe ni ijọ kẹtadilọgbọn oṣu *July* to koja, a ranṣẹ lọ sọ fun Alufa yi ni owurọ lati wa wo bi aisan rẹ ti ri, ati pe bi o ni ọrọ lati ba sọ gẹgẹ bi Alufa ijọ. Nigbati a si reti rẹ ti a ko ri fun ọjọ mẹta, a tun ranṣẹ lọ pe ni owurọ ọjọ kẹrin o si to iwọn agogo mẹjọ alẹ ki o to wole de bi ẹni iti ogun bọ ṣugbọn akoko lati bi lere nipa ti igbala ẹmi rẹ ati lati gbọ ọrọ igbẹhin lẹnu rẹ ti kọja.

Nigbati a jade oku ni ọjọ kẹta oṣu *August* ti a wa yi, lẹhin ti Alufa yi gun ori aga Iwasu tan, o sọ iru enia Ọlọrun ti iya wa yi jẹ ati bi ko ti nfi owo dida rẹ jafara. Lẹhin ti o sọ eyi tan nkan kini ti o ya wa l'ẹnu lati gbọ lati ẹnu Alufa yi ni pe, Iya yi ki ṣe ẹniti o le ku ni akoko yi, on si ri pe awọn ọmọ rẹ ko

tọju rẹ ni o ṣe ku, nwọn ko ra *wine* fun lati mu tabi oriṣi ọti Oyinbo miran ṣugbọn nwọn gba Dokita Oyinbo fun ṣa o.

A dupẹ ni ọdọ Ọlọrun pe Iya wa di ẹni ọdun mọkandiladọrin (*69 Years*) ki o to fi aiye silẹ, awa si mọ adun bi Iya wa ti ri, a si tun dupẹ lọwọ Ọlọrun pe, Iya papa mọ pe a ṣe itọju on de ipo gere, o si ni inu didun si wa tobẹ ti o ranṣẹ pe Alufa J. Wright ti Ijọ *Salem* loju ẹniti o sure fun wa ti o si to gbogbo nkan rẹ bi o ti fẹ ki o ri lẹṣẹṣẹ nigbati o ba fi aiye silẹ. O ṣoro fun Alufa yi lati mọ nkankan nipa awa ati Iya wa nitoripe ile rẹ ki ṣe ile ti o ni igbadun fun lati ma lọ, ati pe ṣiwaju akoko yi Iya wa ṣe aisan pupọ ti Alufa yi ko jẹ wa lati wo tabi ko tilẹ bere egbogi ti a nlo fun. Lẹhin ti o dide ninu aisan ni bi oṣu mẹrin ti o kọja, o lọ dupẹ ni Ile Ọlọrun, lati ọjọ isimi na ti o lọ dupẹ, ko tun ni anfani lati tun lọ si Ile Ọlọrun nitori aisan titi di akoko iku rẹ yi bẹni Alufa yi ko de ibẹ titi o fi di akoko ti a lọ pe lẹkeji ti o fi wa lalẹ ọjọ ti ko fi ba ohun lẹnu rẹ mọ. Bawo ni iru Alufa yi ṣe le mọ pe a ko tọju rẹ.

Ọrọ keji ti Alufa yi sọ ni pe nigbati o si ku tan nwọn wa ko Ilu si ita nwọn bẹrẹ si jo nwọn si pa malu, nigbati o ba si ṣe nwọn a gbe ile ẹni to ku ta lati fi san igbese owo Posi tabi owo aṣọ oku tabi owo malu ti nwọn gbalawin ni Sango, bayi ni Alufa yi sọ oriṣirisi ọrọ ti o fẹ lati fi tẹ ifẹ ọkan rẹ lọrun.

Awa dupẹ lọwọ Ọlọrun pe awa ko gbe Iwe ile iya wa sode ki a to sin oku rẹ, a ko si gba awin ohunkohun lọwọ ẹnikẹni, bẹni a ko ya'jule Alufa Ọṣọ-Olowo igando yi lati wa gba tọrọ (*3d*) lọwọ rẹ.

Akoko ti a wa yi jẹ akoko ti o yẹ fun olukuluku enia lati ma ro ori rẹ ki o to sọ ọrọ tabi ki o to hu iwa. Iba dara pupọ fun Alufa yi lati ma wa idi ohun gbogbo daju gẹgẹ bi ọrọ Ọlọrun ti wi *Matthew 9. 16 & 17* ki o si ma di otitọ mu, ki o si dẹkun ati ma fi ọti titun sinu ogbologbo igo. Iba ṣe ẹtọ fun Alufa yi ati awọn ojiṣẹ Ọlọrun miran ki nwọn le ma fi ara wọn fun agbara Ẹmi Mimọ nigbagbogbo pẹlupẹlu ti nwọn ba nlọ gun aga Iwasu nitori onjẹ Ẹmi ni nwọn ni lati fi bọ awọn Agutan Ọlọrun ti a fi si abẹ itọju wọn.

Pataki iṣẹ ti o yẹ fun, o fi silẹ lai ṣe, eyi ni lati ma bẹ awọn Agutan Kristi ti a fi si abẹ iṣọ rẹ wo, pẹlupẹlu nigbati nwọn ba wa ninu aisan iṣẹ rẹ ni lati lakaka lati wadi bi ọkan alaisan na ti ri si Ọlọrun tabi si ẹnikeji rẹ, ati lati mọ bi o jẹ ẹni igbala nipa gbigbọ ọrọ igbẹhin ti o sọ ati nipa pipara ribẹ yio fi mọ gẹgẹ bi awọn ọmọ alaisan ti nṣe itọju enia wọn si, nigbati o ba si ku yio ri ohun ti yio sọ sipa ti oku a ati awọn ọmọ oloku pẹlu.

S. A. KING,
G. A. DAVIES.

# This, That, and the Other.

*By an old Crow.*

---

### Mr. J. M. Stuart Young

Imitation, we are told, is the sincerest form of flattery. Had Mr. J. M. Stuart-Young satisfied his "modelling" by refraining from using Professor Carruth's words his position would have been quite clear, at least, to us who are not initiated in the mystery of Literature but form a great majority of the reading public. But when Mr. Stuart-Young steps out of his latitude to *adulterate* a work which has been translated into German, French and Latin, a work already of world fame, it baffles our understanding.

Well might one exclaim with apology to Prof. Carruth (is it to Mr. Young ?) :—

*Stuart-Young calls this "refining"*

*But I—I call it—???*

### Boy Scouts Charged.

The news published in the *Nigerian Pioneer* and subsequently reproduced in the *Elete Ofe* (13/8/24) has created a great sensation in some quarters in Lagos. We hope the Scout Authorities will take the matter in hand especially when Mr. J. R. Oliver, The Scout Commissioner for Nigeria who is now in England on leave is expected to join them here this month or next.

The News item runs as follows :—

**"Arrest of some Boy Scouts."**

"Some Boy Scouts were arrested on the charges of insulting a Court Messenger at Odogbolu 12 miles from Ijebu Ode.

The boy Scouts merely called the messenger's attention to the fact of his riding a bicycle for which he has not got out a licence, and for this, they were summoned before the District Officer's Court. The four boys were fined £1 each, or in default of payment 1 month's imprisonment. Nothing to our knowledge, was done to the Court Messenger!"

### The Nigerian Spectator.

*The Nigerian Spectator* in its issue for 9/8/24 could not help but again congratulate the Hons J. Egerton Shyngle and E. O. Moore, the Democratic Candidates.

"The Honourable Mr. Shyngle" says *The Nigerian Spectator* "is as active as ever in The Council Chamber...."

Well! *a chacum son gout!* as the French man would say; while we appreciate the Editor's fairness on the one hand, we cannot help, on the other, wishing that in future any of our political leaders in Lagos should first of all try to see beyond his very nose—that being done, he can then assume the position of seeing the future of the teeming inhabitants of this country.

In all probability, one need not be a prophet to attain this—need one?

AN OLD CROW.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, AUGUST 16, 1924.

## A BA F' EYI ṢE'WỌ, IWỌ JẸ FẸ? IWỌ JẸ GBA?

Wosika ti awọn Ọgbẹni S A. King ati G. A. Davies ti nwọn ngbe *94, Denton Street* l'Ebute Mẹta fi ṣọwọ si wa fun titẹ sinu Iwe-Irohin ọsẹ yi ti a si tẹ, mu ni lọkan gidigid, tobẹ ti a kole ṣai sọ gbolohun ọrọ meji mẹta si i.

Iṣẹ Alufa ni lati ma wasu gbigbona, iba ṣe ni Ṣọṣi tabi ni Mọṣalaṣi, fun dida iwa ti o ba ro pe ko yẹ Onigbagbọ tabi Musulumi lẹbi, nitori ki awọn ẹlomiran ti nwọn jẹ Onigbagbọ tabi Musulumi ẹgbe rẹ le yẹ'ra fun irufẹ iwa bẹ; ṣugbọn nigbati o ba ṣẹ di ogun Alufa nbẹrẹ si tojubọ ile-onile, nipa sisọ ọrọ ti ko yẹ ipo rẹ, eyini ni nipa sisọ ọrọ aṣiri (*personal matter*) ti ile-onile ṣaka-ṣaka lori Igi-iwasu rẹ—ani ọrọ ti ko kan lọwọ ti ko kan a lẹsẹ, ti o jẹ pe ko si le f'ogun rẹ gba'ri pe otitọ ni—larin gbogbo Ṣọṣi, gidipa ni igba ijade oku, gẹgẹbi ti awọn ti nwọn kọ wosika yi si wa bayi, Alufa na ṣẹ ngbe sara kọja Mọṣalaṣi niyẹn, o si sọ ara rẹ di Bisibeke.

Irohin ti a si tun gbọ pe o kan nipa jijade oku alagba kan ti o tun ku, ti a si gbe lọ si Ṣọṣi kanna l'Ebute Mẹta lọjọ die, lẹhin igbati ọfọ awọn Oni Wosika yi ti ṣẹlẹ—makan-makan ṣa l'oye nkan—ni pe rọ ti Alufa Oni waduwadu yi ti tori rẹ doju ti awọn iyekan pẹlu awọn ojulumọ ati ọrẹ ti nwọn kọ jade oku ti wọn, ni Ṣọṣi kanna lakọkọ, ohun kanna gan ni a si gbọ pe awọn Ẹbi (*Family*) oku keji ṣe; nṣe ni a sọ pe Alufa yi pa "pẹnrẹn jẹ" nigbati o nwasu ti o si gb'ẹnu le ọrọ ti awọn Ọlọfọ keji yi; kaka bẹ okuru ọrọ forifọri lo nsọ; nigbati Ṣọṣi si jade tan, a gbọ pe ko beni-beji ki o to ba awọn ọlọfọ keji na lọ si'le ninu Agbada rẹ!!!—Eyi ara—ti o si gbadura fun wọn; eyi ti ri? O ha jọ pe agbara A pe kanu-ko, lo ndun baun? Awa ko mọ; irufẹ iwa ti awọn Oni Wosika na ṣ'aroye rẹ yi, mu ni ranti iwa Alufa kan ni'lu okere kan l'ọjọ to ti pẹ. A sọ pe o jẹ aṣa Alufa yi lati ma gbe lankẹ ẹnikẹni ninu *Member* rẹ ti idawo ọdọdun rẹ sinu apo Alufa ba "bẹ ṣuọ," nipa lilọgun orukọ ẹnibẹ fun gbogbo *Member* lati gbọ; nigbati o di ọdun kan Ọgbẹni Agbẹ roko-kura kan ti o b'ode pade l'ọdun na da adọta pọun (£50) sinu apo yi ni Ṣọṣi rẹ; nigbati ipade ọdun pe tan, ti Alufa yi fẹ bẹrẹ si pe orukọ awọn ti o da'wo, bẹni o kigbe lohun rara pe Bandele Ọlọla—Ẹ ko ngbọ igi-la-ngọ ọro, ẹnyin ara ibi, Agbẹ ṣa ma ni ẹniti a wi yi o, ko si ni ipo kan ni'lu, a nbọsi-bọsi ipo ọla—da adọta pọun; nitorina ẹnyin ara mi, ẹ da Muso l'ẹmẹta fun u, ki ẹ ṣapẹ; bi adiẹ ko s'ọka, awọn *Member* si ṣe bẹ, ngbọ, ina njo, a nfẹ. Nigbati o di ọdun keji, Ọgbẹni Agbẹ yi da pọun mẹwa (£10) igba ko ṣa lọ bi orere—nigbati o si di Ajọdun keji ti Alufa yi ma darukọ rẹ, kilotiwi? O ni Ọgbẹni Bandele da pọun mẹwa; Alufa yi ko tilẹ fi atẹwọ lọ ọ lọtẹyi ṣugbọn awọn *Member* ti nwọn ki nṣe "ẹru aje" ṣapẹ fun u bakanna, laijẹpe Alufa na yọda rẹ

Nigbati o wa di ọdun kẹta wa yi o, ti ọkakara wọ'le okokoro fun Agbẹ yi o sa'pa da ṣile marun (*5/-*), nigbati o si di Ajọdun kẹta, nṣe ni Alufa yi wipe Agbẹ kan da ṣile marun, ko tilẹ darukọ rẹ bi ti iṣiwaju; wara-were nṣe lo si tu ipade ka lojiji nipa ṣiṣe "Ore-ọfẹ": awọn *Member* na si wo ara wọn loju pe, kilode? Ẹnyin ara, Ẹ ri agbara Kudi bayi tabi ẹ ko ri? Abọ wa niyi o. Ninu ohunkohun gbogbo, o yẹ ki awọn Alufa k'Alufa ma gbidanwo lati ma f'ẹmi ibani kẹdun han awọn "Agutan" wọn l'ọna gbogbo.

Ohun ti a sọ nibi a sọ fun gbogbo ẹnyin Alufa t'oku, Ẹ ma ṣọra !!!

---

**T. A. Erinosho,**

*Forwarding, Shipping, Buying, Selling and Commission Agent, Land and Estate Agent. Produce Merchant.*

*Licensed Auctioneer & Valuer.*

19, Tinubu Street, P.O. Box 242,

Lagos, Nigeria.

## AT'ARÉDÉ, AT'ARÉDÉ, K'A GBỌ TI JESU RE MO MỌ!

(Part 2.)

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Li ọsẹ ti o kọja, a sọ diẹ nipa isoro ti o wa ninu Ofin Ikọsilẹ (*Divorce,*) Ofin Ipinya (*Judicial Separation,*) Ofin Ọdaju (*Restitution of Conjugal Rights,*) Ofin Owo Ọṣọṣu (*Alimony*) ti ọkọ nfun aya lẹhin ipinya tabi ni akoko ti ẹjọ awọn mejeji wa ni Kotu, a sọ ti jijẹ ti aya le jẹ oruko mọ ọkọ rẹ lara lẹhin ikosilẹ ati titi o ma fi ku, ti o ba fẹ; a fihan wipe iyawo ti a ngbe ko nṣe ti Onigbagbọ (*Christian Marriage,*) a tun sọ wipe ara Ilu Gẹsi ko le gbe ti Jamani ni iyawo, bẹni Faranse ko le gbe ara Itali laitẹle ilana ofin ile Ọkọ-iyawo, bi o ti wu ki igbagbọ w[illegible] le gbona to, a si tun sọ orişirişi ọro miran pẹlu nipa arede ati ofin arede ti ko ba ti Bibeli mu.

Nisisiyi, nwọn ngb'ero ni Ilu Oyinbo lati yi (*revise*) Iwe-adura (*Common Prayer*) pada diẹ, papa ilana ẹsin igbeyawo, nwọn si npete ati yọ majẹmu tabi ileri aya lati tẹriba (*obey*) fun ọkọ rẹ kuro nibẹ, ki a to gbe iyawo fun wọn.

Idi ero iyipada (*revision*) yi ni pe, nwọn ni aya ko ni lati tẹriba fun ọkọ, tabi ki o gbọ ohun ti ọkọ ba wi, ayaşebi aya na şe ohunkohun ti o ba wu u, nitori ẹgbẹ ni awọn mejeji—ọga nta, ọga nra ni wọn.

Eyi le di ofin arede laipẹ. Bẹni nigbati "Olọrun nsure ni Eden, ni igbeyawo kini," O paşẹ fun Efa pe, "lọdo ọkọ rẹ ni ifẹ rẹ yio ma fa si, on ni yio si ma şe olori rẹ." St. Paul pa ofin yi mọ nigbati o wipe, "*The wife should be in subjection to the husband.*"

Eyiti Oluwa wi, ti St. Paul si juba rẹ, awọn Oyinbo ngb'ero nisisiyi lati gbe e ti si apakan nitori ifẹkufẹ wọn. Ki ọkọ ma le sọrọ fun aya ti o wa labẹ orule rẹ, ti o ngbọ bukata ati jẹ, ati mu lori rẹ, eyi şe kelebo; nitotọ, Ọlọrun nikanşoşo na lo le şe idajọ a-t'ehin-pin ẹran.

Ofin arede ti a o gb'enu le pataki ni ọsẹ yi ni [illegible]ọ ti Kotu nkọ lati fun ọkọ ni Iwe-ikosilẹ ava [illegible] ẹri (*evidence*) tabi ẹjọ ti ọkọ ro wipe on ko [illegible]nmọ iyawo on titi o fi fẹ'ra-ku, ti o si bimọ fun Bab[illegible]-isalẹ rẹ. Ofin yi lo jẹ idina ni lọlọ yi fun ọmọ[illegible] ọlọla kan ni Ilu Oyinbo, *The Honourable* John Hugo Russel, akọbi *Lord* Ampthill, ti ko si [illegible]ki o le kọ iyawo rẹ Christabella Russel silẹ, [illegible]iti ọkọ rẹ, ọmọ ọlọla yi wipe, o bi ọmọ ale.

Owo ti ọkọ yi, *The Honourable* John Hugo Russel bajẹ si Kotu ati fun awọn Loya lati le kọ aya rẹ silẹ le ni Ẹgbẹrun ọna adota pọnwun (*£50,000;*) sibẹsibẹ, pabo ni! Ofin ko yọda ikọsilẹ na.

Ọrọ na lọ bayi:—Ni ọdun keji ọhun, 1922, *The Honourable* J. H. Russel pe aya rẹ l'ẹjọ ikọsilẹ, o si wipe, ọmọ ti obirin na bi, ko nşe ọmọ on, bikoşe ti Baba-isalẹ. O haya Lọya nla nla mẹrin, Ọgbẹdi Ọlọla *Sir* Edward Marshall Hall jẹ ọkan ninu wọn. Owo-işẹ (*retainer*) ti on nikan jẹ Ẹgbẹfa pọnwun (*£1,200*) pẹlu ele adọtalerugba pọnwun, adọtalerugba şile lojojumọ ti o ba lọ si Kotu fun ẹjọ yi. Iyawo rẹ na haya Lọya mẹrin. Kotu pe Juri si ọrọ na: nigbati nwọn ro o lọ siwaju, sẹhin, ẹnu awọn Juri ko ş'ọkan, nitorina, ẹjọ sun.

Lẹhinna, ni *February 28th*, 1923, o nlọ si ọdun kan abọ loni, a tu ẹjọ yi palẹ, a si ro o fun ọjọ mẹwa gbako. Ẹjọ ọkọ jare, Kotu si fun u ni Iwe-ikọsilẹ aya rẹ.

Mrs. Russel, iyawo rẹ, ni idajọ yi ko tẹ on lọrun, o ni on fẹ "ja-aja-gbula" apil (*appeal*) lọ si Kotu Onidajọ mẹta. Awọn Lọya njẹ owo l'ọtun, l'osi, şugbọn gẹgẹ bi ofin arede Oyinbo, gbogbo ata owo ti f'ọko-t'aya nlọ fun Lọya, ọkọ ni Olube ti a o fa a si l'oju.

Ni ọjọ kẹtale-logun ati ikẹrinle-logun oşu *April* ọdun ti o kọja (*23rd and 24th April, 1923,*) awọn Lọya t'ọtun-t'osi fi pẹki ko pẹki niwaju Onidajọ mẹta ni *Court of Appeal*, Kotu ti o da Oloye Oluwa l'are nijelo.

Lọya aya ro ẹjọ, ti ọkọ ro, Kotu Onidajọ mẹta si ho yegede bo aya—Yegede! Itiju ni aya ba kuro ni Kotu li ọjọ na.

Şugbọn, Ofin arede Oyinbo, Ofin Tulasi ni. Tulasi ni on fẹ ba alarede gbe, o ni ko si aye, Tulasi ha kọ gongo imu Mr. *For better* ati Mrs. *For worse* iyawo rẹ?

Mrs. Russel ni idajọ ti Kotu Onidajọ mẹta ko tun tẹ on lọrun. O ni ẹjọ ti nwọn da, nwọn da a si apo ara wọn ni, ati pe nitorina, on tun fẹ ja-aja-igbula *appeal* lọ si *House of Lords* tabi olubori gbogbo Kotu ti o wa ni Ilu Oyinbo Gẹsi. O sa ti mọ daju pe, gẹgẹ bi Ofin, on jare ni o, tabi on jẹbi, owokowo ati iyekiye ti on ba na fun Lọya, ati eyiti on ba sun ọkọ on na, ọkọ on nikan ni yio san gbogbo rẹ patapata, o fẹ, o kọ.

Ni olubori Kotu, *House of Lords* yi, Onidajọ marun lo wa nibẹ. Awọn mararun yi ju Amofin tabi Lọya lo, gẹgẹ bi *Eko Akete* ti sọ fun wa nijelo pe Ologbe Lemọmu Buraimọ jẹ "Jinu" ninu Keu, bẹni awọn mararun yi jẹ "Jinu" ninu Ofin.

Lẹkan si i, Lọya ọkọ pẹlu ti aya tun pade niwaju awọn Anjọnu marun ninu Ofin wọnyi, nwọn ro, ro, ro, ro, nwọn sọ, sọ, sọ, sọ, epe lo ku ki nwọn şẹ; nigbati o si di ọgbọn ọjọ oşu *May* ọdun yi, iyẹn nlọ si oşu meji abọ nisisiyi, mẹta ninu awọn Onidajọ marun yi fi are fun aya; meji ti o ku, *Lords* Summer ati Carson da ọkọ l'are, şugbọn nigbati awọn Onidajọ ti o wa lẹhin aya ti pọ ju ti ọkọ lọ, ẹjọ ọkọ jẹbi niyẹn; nitorina, Iwe-ikọsilẹ ti Kotu Onidajọ kan pẹlu awọn Juri mejila ati eyiti Kotu Onidajọ mẹta ti yọda *fun u şiwaju* di oku mọ ọ lọwọ—oku ti ẹlẹja nta a.

Kil'o jẹ ki ọkọ to fẹ lati kọ iyawo rẹ silẹ nitori o wipe o ṣe panṣaga, o si bi ọmọ ale jẹbi bayi? Ofin arede ni, ofin yi ni mẹta ninu awọn Onidajọ marun tẹle. Ofin na wipe, bi ọkọ ko tilẹ sunmọ iyawo rẹ ki o to bimọ, ko gbọdọ sọ bẹ ni Kotu, bi o ba si sọ bẹ, Kotu ni lati ka a si ọrọ aimọ, eyiti ko to nawi.

Lori ẹjọ ti Olubori Kotu *House of Lords* gbe gba'gi fun ọdọmọkunrin ọmọ ọlọla yi, *The Honourable* John Hugo Russel, owo pupọ ni o ti bajẹ si idi rẹ. Ọkan pataki ninu Loya rẹ, Ọlọla *Sir* Edward Marshall Hall, K.C., jeri si eyi nigbati o wipe:—"*It was the general practice of the Divorce Court that a husband involved in proceedings for a divorce had to pay his wife's costs even if he succeeded. Mr. Russel had already paid £8,64a to his wife's solicitors for taxed costs, and he had still to pay the costs of the appeal and the proceedings in the House of Lords and there were his own costs of the two trials. The total liability could not yet be ascertained, but it must exceed £30,000.*

Itumọ eyi ni wipe,—Ofin Kotu Kọ'kọ-kọ'kọ, tabi Ka'ya-ka'ya, ni pe ọkọ nikan lo ni lati san gbogbo owo iṣẹ Loya ti ara rẹ ati Loya ti iyawo rẹ ti yio tako ọkọ ni Kotu, bi o tilẹ ṣe wipe ọkọ lo jare. Ọgbẹni Russel ti san ẹgbẹrun mẹjọ, o le ojile-lẹẹbẹta ponwun fun Loya aya rẹ, o si tun ni lati san owo Loya iyawo rẹ fun titako ti nwọn ta ko Loya tirẹ ni Kotu Onidajọ mẹta ati ni Olubori Kotu, lẹhin ti o ba san owo iṣẹ fun awọn Loya tirẹ papa tan. Gbogbọ owo to ku diẹ ti Ọgbẹni Russel ọkọ iyawo yio san le ni ẹgbẹrun ọna ọgbọn ponwun £30,000, sibẹsibẹ, Kotu da a l'ẹbi wipe, ko le kọ iyawo rẹ silẹ!

Bi ofin arede ti ri niyẹn, ọmọ ọlọla Ilu Oyinbo ti o na ẹgbẹrun ọna adota ponwun (£50,000) lati kọ iyawo rẹ silẹ ṣe e ti, melomelo iwọ Kosalabaro, Makunnu Ọlọrun.

A mọ wipe ko si ẹniti o ngbadura amubọ; ko si ẹniti o nfẹ obirin nitori ati kọ ọ silẹ nigbakigba to ba wu u, ṣugbọn t'ibi-t'ire ni a wa si aye; bi enia ba nro rere, ko tun ma rọ rere ọna keji pẹlu nitori albamọ, ẹgbọn ẹhin ọla!

Lẹhin ti olubori Kotu ti da ọmọ ọlọla yi lẹbi tan, Ọgbẹni miran ni ilu Oyibo ti orukọ rẹ njẹ *Wood* pe aya rẹ l'ẹjọ ikọsilẹ ni oṣu June, oṣu keji to koja. Ọgbẹni yi haya Loya, o si sọ fun onidajọ pe o gbe aya on ni iyawo ni ọdun kẹfa, 1918. L'ọdun keta *September*, 1921, iṣẹ gbe on lọ si ilu kan ti a npe ni *Mesopotamia*, nibẹ ni on si wa titi di ọdun yi. Bi o ti ṣẹṣẹ fẹ sọ pe nigbati on pada de, on ba ọmọ oṣu mẹfa lọwọ iyawo on, bẹni Onidajọ ta ko o wipe, on ko ni gba ki ọkọnrin k'ọkọnrin sọ niwaju on pe on ko si ni ile, tabi pẹ iṣẹ gbe on lọ si idalẹ nigbati iyawo on loyun, to si bimọ, nitoripe olubori Kotu *House of Lords* ti fi aṣẹ si i ninu ẹjọ ọmọ ọlọla *Russel* ati iyawo rẹ pe, Kotu ko gbọdọ gba ẹri (*evidence*) ọkọ mọ pe on ko sunmọ iyawo on, nitori alarede ko le bimọ ale, ayaṣebi a ri ẹri pataki miran ti ko nṣe ti ọkọ.

Ẹ maṣe wipe ofin arede ilẹ yi yatọ si ti ilu Oyibo nipa ẹjọ ikọsilẹ, alarede k'alarede to ba si wipe bẹkọ, ko gbidanwo. Gẹgẹ bi a-ka-hin, nigbana lo ma mọ wipe yangi ko nṣe ẹwa nigbati o ba fi s'ẹnu.

Ofin k'ofin yi ko ha tun fi han gbangba pe arede ti a npe ni ti onigbagbọ, ti Oyibo ni patapata? Kilo ṣe ti awọn ọba wa ko ngbe arede? Eyi jẹ ki nranti akoko ti ologbe Gbadebọ Alake lọ si ilu Oyibo, ti Oyibo kan si nbere pe "*Where is Mrs Alake*" Iyawo alarede Ọba Alake da? Mo tanma pe Ọlọla Adegbọyega Ẹdun ni ọrọ yi yio pa l'ẹrin ju.

Alarede pupọ ni ko mọ ohunkohun nipa ofin arede, pupọ ninu Afa Ṣọṣi papa to ngbe iyawo fun ẹni ẹlẹni lo si jẹ ọgbẹri patapata ninu ofin na, ti won ko ju ikilo pe Ẹni ti Ọlọrun ba so pọ, ki ẹnikẹni ma ṣe pin won ni iya; *Whomsoever God hath joined together, let no man put asunder*; bi t'ọkọ t'aya si nja ajatuka lẹhin na ni Kotu, eyini ko kan Alufa mọ.

Wahala ati inira kekere ko lo wa ninu ofin arede, nwọn pọ tobẹ gẹ ti talaka ko gbọdọ daba ati kọ iyawo rẹ silẹ, bi o tilẹ nṣe panṣaga loju mejeji, ayaṣebi ọkọ na ba lowo ati haya Loya fun ra rẹ, ko tun haya fun aya rẹ ki o si fi owo tiantian silẹ, ti iyawo yio ma jẹ titi ẹjọ yio fi pari. Lẹhin ti ẹjọ ba si pari tan, nigbana ni ọkọ tun bọ si inawo nla-nla, owo irin ẹsẹ.

A mọ ẹniti o gbe ile ta n'ilẹ yi nitori inawo ẹjọ ikọsile to nba iyawo rẹ ro nigbana; asinwa, asinbọ, Kotu kọ lati fun ni iwe ikọsilẹ nitori pe ọk papa ti bi'mọ sodẹ. Titi di oni oloni, obinrin n njẹ orukọ mọ ọkọ rẹ, o si nbimọ lọwọlọwọ yi fu baba isalẹ. O di ari i gbọdọwi si ọkọ l'orun-ikun imu egbere.

Boya nitori wahala ati inira yi lo jẹ ki ọdọmọkọnrin kan laipẹ yi fi oṣi le ọdaju to si gba ado *pound* £150 lori aya rẹ lọwọ Ale to si fun ba isalẹ aya rẹ yi ni iwe pe on ki yio pe e lẹjọ. A gbọ pe obinrin ti a nsọrọ rẹ yi bi ọmọ kan meji fun ọkọ rẹ, o si ṣẹṣẹ bi jojolo kan fun al nisisiyi.

A ko da orukọ ẹnikẹni, bẹni a ko sọ eyi la aṣiri ẹnikẹni ninu awọn mẹtẹta, bikoṣe gẹgẹ apẹrẹ iṣoro ati inawo to wa ninu ẹjọ ikọsilẹ alare iṣoro to njẹ ki ọpọlọpọ ọkọ jiya lori iya.

Ofin arede miran ni eyi:—Bi ọkọnrin kọ i si obinrin lati fẹ ni ireti a ti gbe e ni iyawo, y o fi iwe sọ bẹ ẹ ni o, tabi iwa tabi iṣesi, to b obinrin na silẹ lẹhinna bi *wagon* obinrin le lẹjọ fun Idalọwọkọ (*Breach of promise*) o si le on fẹ gba ọgọrun, tabi igba, tabi ẹdẹgbẹta,

gbẹrun pound lọwọ ọkọnrin nitorina, Kotu yio si fi ilẹ si i gẹgẹ bi ipo ọkọnrin na ba ti to, ati bi iye owo ti obinrin le ri jẹ lọdọ rẹ, bi o ṣe pe o gbe e ni iyawo, bẹni Kotu le bu iye owo ti ọkọnrin ni lati san fun obinrin ti iwa rẹ ko wọ ni tirẹ lati gbe ni iyawo.

Nitori eyi, a o kilọ fun awọn *Boys* ki nwọn ṣọra gidigidi nipa "*love letters*" ti nwọn nkọ si awọn *girls*, ki awọn *girls* pẹlu kiyesara nitori———

Diẹ ninu ibi to wa ninu ofin arede Oyibo ni a ka silẹ yi; Alufa Ṣọṣi ki Ṣọṣi to ba wipe bẹkọ, ki o ja mi ni koro, ki o si tẹ ẹ sinu iwe irohin ki iwe irohin to ba fẹ, ati ni edekede, ibaṣe ede Oyibo, ede Yoruba, tabi *Arabic*—Keu.

Pẹlu gbogbo ibi yi, arede Oyibo fun Enia Dudu ko ṣai ni anfani tirẹ, ani anfani "*For better for worse*", anfani ikẹ ati igẹ nile, ko si owu jijẹ (*jealousy*) ko si wahala orogun, ko si ti ọbakan, ko si wahala ana (*in-law*) bẹrẹbẹ. Ọkọnrin to ba ti sinku ana mẹta tabi mẹrin ri lo mọ riri ohun ti a nwi yi daradara; ọkọnrin to ba si ti ri nkan ti awọn orogun meji miran nfi oju ara wọn ri, lailai, ki yio fẹ aba ati ni aya meji.

Bi o ba t'ọkọ t'aya nile miran, nwọn dabi ọmọ iya kanna, ṣugbọn awọn to dabi ina pẹlu ẹtu si ra wọn lo pọju. Ọlọrun ko maṣe ti ẹnyin ọkawe wa bẹ ẹ.

Lẹhin ti a ti fi ibi ati ire to wa ninu arede Oyibo han bayi tan, ọkan wa fuyẹ; sibẹsibẹ ẹru aba wa pe yigi ti awọn Musulumi nsọ, ko mu itanjẹ ati agabagebe dani fun Enia Dudu bi arede Oyibo, afi olotó alarede to mura tan lati pa gbogbo ofin arede mọ, ko si joko ti obinrin kanṣoṣo titi iku yio fi ya nwọn, ti ki yio si "*Rasputin*" fun obinrin miran ni ikọkọ, bi bẹkọ iwọ alarede ti o nka iwe yi, olori agabagebe ni ọ! ẹri ọkan (*Conscience*) rẹ nsọ fun ẹ bẹ ẹ !!

At'arede, at'arede, k'a gbọ ti Jesu re mo mọ! Ni ilu Oyibo arede obirin kan ni nwọn nfẹ nibẹ. Sibẹsibẹ, ẹnikẹni to ba fẹ mọ Ilu ti iwa aimọ *immorality* ati iṣekuṣe *prostitution* pọju l'aiye, ki oluwarẹ na lọ si ilu Oyibo, yio wo iran wo'ran titi, itọ a kan l'ẹnu rẹ.

Nwon tilẹ ni ile pataki fun awọn "Aṣẹwo nibẹ", aragbabu si ni iru ile bayi to wa ni ilu Franse Wọbu ni ọmọ ale kun ilu Oyibo, awọn "ọmọ kan, baba mẹfa", laika ọkẹ aimọye awọn ọmọ gọta ti a ko tilẹ mọ baba wọn rara.

A ko le ba awọn obirin nwọnyi wi pupọ, nitori lẹhin igbati ọkọnrin kọkan ba ti gbe obinrin kọkan ni iyawo tan, obinrin to ṣẹku silẹ to ilọpo ọkọnrin ni ọna mẹta tabi mẹrin. Boya pupọ ninu wọn nfẹ lati bi ọmọ, ṣugbọn ọkọnrin ko si lati gbe wọn ni iyawo, ewo ni ki nwọn ṣe? Bẹ gẹgẹ si ni ọpọlọpọ obirin nilẹ yi nfẹ gbe arede, ṣugbọn nwọn pọ ju ọkọnrin lọ, nitorina bi ọkọnrin kọkan tilẹ gbe ẹni kọkan wọn ni iyawo, awọn to ba ku silẹ nkọ? Tabi gbogbo wọn lo ma kuku di 1itia amọbiowo, amọbiowo wa ni Tẹsi.

Anu pupọ ninu awọn ọmọdebinrin wa nṣe mi nipa ọrọ ọkọ fifẹ, ẹlomiran ninu wọn to tilẹ lọ si ilu Oyibo koi ri'kan ṣe'kan titi di isisiyi. Adura wa ni pe ki Ọlọrun pese ọkọ anfani fun gbogbo wọn.

Ju gbogbo rẹ lọ, ọna ti awọn enia wa fi ngbe arede yatọ si ti Oyibo, ko si ba ti ilẹ wa mu. Oyibo ko ngba orogbo, Oyibo ko ngba obi, atare, oyin, aṣọ oke. Aṣa ti ilẹ wa ni eyini, nitorina amulumọla iyawo ni a nṣe. Oyibo ko nda aṣọ ẹbi, wọn ko nra aṣọ ti iyawo won yio wọ nijọ iyawo, awọn enia iyawo papa lo nṣe inawo yi fun ra wọn, Oyibo ko nda aṣọ ẹbi, Oyibo ko njẹ iya ọkọ; aṣa ti ilẹ wa ni nwọnyi, ṣugbọn pẹlu gbogbo rẹ, a ko jẹ oṣaka, a ko jẹ oṣoko.

Lakotan, mo kesi Biṣọpu, mo kesi gbogbo Afa Ṣọṣi, ki wọn wa ọna lati fi ofin arede ye gbogbo mẹmba wọn ti koi gbeyawo, ki nwọn sọ ibi ati ire to wa ninu rẹ fun wọn, papa fun awọn ara ilu oke, Ijẹbu, Ẹgba, Ijẹṣa, Ondo, Ifẹ, Akurẹ, Ogbomọṣọ, Idanre, Oke Igbo, ati ilẹ Yoruba miran, ati gbogbo awọn to wa lodo Ọya, ki nwọn to ma fi ajaga arede kọ wọn l'ọrun, ninu aimọkan wọn.

At'arade, at'arede, ka gbọ ti Jesu re mo mọ!

Emi ni tinyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## ABURANDA TO BAJẸ TITUNṢE!

ESI SI IWE-IROHIN "AFRICAN MESSENGER."

[*Lati ọwọ* GBARUKU.]

Ti ẹniti o kọwe nipa wa si inu Iwe-irohin *African Messenger* (7/8/24) ba bere lọwọ awọn to ju lọ—nitoripe a ro pe ọmọde kekere ni on papa nipa ọrọ ẹnu rẹ—awọn agbalagba to ni oye julọ yio sọ fun pe otitọ ni *Gbaruku* nsọ nwọn yio si tun tọka apa ibi ti Aburada ta nwi yi gbe bajẹ si fun.

Gbolohun meji ti ọmọde yi fi pa ara rẹ l'ẹpa niwọnyi:—Ekini, ara'le-wa ni ti Lọya Agusto fi lọ t'o fi bọ, on ko gbọ lẹnu ẹnikẹni ati pe Lọya na papa ko sọ pe on kọ mimọ ẹsin bọ tabi pe on lọ si Ile-kewu lọhun. Ekeji, o ni, bawo ni *Gbaruku* ti ṣe sọ pe b'oti wu ni l'a ṣe Imale ẹni.

Ti ọmọde ko ba de oko miran ri yio sọ pe ko si oko ti o to ti baba on—aileja si ni a ko ba ọmọde ja—mo bẹrẹ f'oji o, gbogbo ẹnyin Janmọ ọkawe wa—nitori eyi, a o fi ọmọri de iya igba meji ti akọwe inu *Messenger* yi mu wa.

Ekini, a fẹ ki o mọ pe ilu Oyinbo ko dabi Eko, nitorina, a ko ro pe akọwe yi nreti lati gbọ pe Lọya Agusto lọ si iru Ile-kewu bi ti Alaji Belo

nita Șita, ti Alufa Ọlọrun-ko-bun-mi-loko ti Ita Balogun tabi Ile-kewu Lala. Aparę la fi iwọnyi șe o.

To o! emi *Gbaruku* sọ pe Lọya Agusto kọ mimọ ęsin Islam bo lati Ilu Oyinbo. Mo fọwọ sọ'ya fun kan yen, mo si fę ki Akowe *Messenger* na mọ pe agbajọ ọwọ la fi nsọya. Ọjọ gbọrọ lo fi gbe Mọșalași *Ahmadia* ni *London*. O si ti je'ju ko awọn Ogun-na-gbongbo inu *Ahmadia* o si ti ba wọn sọ ọrọ toto ọcọ nipa ęsin. O ti ri awọn ti o tilę ję wipe nwọn sunmọ *Ahmadia* pękipęki tobę ti nwọn le ni *Ahmadia* papa ni oruko awọn nję. Eyi ni awọn Oyinbo npe ni *a study at close quarters.* Ka tilę da silę ka tun șa—Agusto kọ ęsin ko ko ęsin, a wa le fi we emi *Gbaruku* tabi *Arale-wa* ti ko de Okun Alasia, ka ma șęșę sọ pe Ilu Aganyin? A wa le fi ęniti o ti ri awọn ti o nkọ iwe ęsin ti awa nka nilę yi ti o ti ba wọn sọrọ we awa ti a nra Ęlędę apo ni'lę yi?

Esi gbolohun keji ni wipe ni otitọ b'oti wu ni I'a șe Imale ęni; mo si ro pe ęnikęni yio jęri mi pe emi kọ lo da owe yi silę.

Mo fę lati fun Akọwe na ni apęrę kan nitoripe ...ọn ọmọde ki le tete fi oye gbe ọrọ lalai si ...un ti Oyinbo npe ni *example*:

...ęnyin ę wo igbati awọn ęgbę *Ahmadia* bęrę ...kawọ si aiya ni'jelo. Gbogbo Imale Eko ...ọ lo nsọ pe awọn ko fę awọn ko gba? Awọn ęgbę *Ahmadia* da wọn lohun? Ofin wo lo mu awọn ęgbę yi si? Bo ti wu wọn kọ ni nwọn ...e yęn? Mo nduro de esi o!

Abawun Ajapa ni ọn ni aya męta!—nwọn ni irọ!—O ni Yanrinbo!—nwọn ni eni!—Oni ki nwọn ja yęn na—Toto fun u!!!

GBARUKU.

---

## WHEN GREEK MEETS GREEK—WHAT THEN?

Lest we be charged with the 'sin' of onesidedness relative to the Rt. Rev. Bishop S. A. Coker's Rejoinder, the first instalment of which appears in these columns, we shall publish in our next issue excerpts from the Presidential Address delivered by The Rt. Rev Bishop A. W. Howells D.D. to the Niger Delta Church as published in the *Diocesan Magazine*, pages 142 and 143 for July, 1924, regarding the subject at issue.

We would ask our readers, when reading both the Rejoinder and the excerpts to recall to mind, this well-known Latin aphorism, *Ab Uno, Disce Omnes*, i.e. from one instance judge the rest.

[ED. E. A.]

## PRELATE JONES'S DECLARATION OF A HOLY WAR!

AGAINST AFRICAN CHURCHES.

BY *Bishop S. A. Coker.*

---

*No. II. (No. I published in "African Hope" for July.)*

Prelate Jones, instead of the White Flag and preaching peace has flown the Red Flag preaching Fire and a Carnal War against African Churches. It is doubtful whether this prelate is cognizant or cares to know the object of the establishment of Missionary Societies in England where he hails from some 31 years ago, which object in few words is, to preach the *Gospel* in obedience to Christ's Command. The object was not to preach the tenets of a particular Church Organization of foreign mould and imbued with their National instincts, customs and idiosyncracies. The Gospel of Christ is not a Church Organization. "Go ye into all the world and preach the Gospel to every creature whosoever *believe baptize*, "is the Gospel of Christ, Converts and believers are to be baptized" conversion is the work Christ is not responsible for national Councils of the Holy Spirit and not of any man, white or black, bishop or priest Synods, Conferences and Man's formulated Creeds, God is not ignorant of the different idiosyncracies of His creatures and effect of climes and other condition. Christ did not require that His Gospel was to give special preferences to some tribe or nation in matters of social systems and customs; systems and customs mostly owe their existence to climate and peculiar environments. Christ during His three and a half years' mission never preached against polygamy nor condemned it as a tribal custom; He never legislated for Marriage as a function in connection with His Mission; He preached nothing of the so-called sanctity of Marriage *i. e.* Marriage in Church. He attended the Marriage of a relative in Cana of Galillee in the house of the bride; He did not propound any doctrine about Marriage nor did anything amounting to an *official act*. The plain and simple commandment of God which He, Christ, supported and upheld and which He summed up in the few words, "Love to God and love to Man;" and this the first Misionaries Apostles preached—He did not state that forth-coming generation of some special nationality will be authorized and empowered to enlarge upon this commandment or legislation that other nations must submit willy-nilly to their pronouncement on Salvation of souls, such as *polygamy, Church Marriage* and so-called *sanctity of Marriage.*

*(To be continued.)*

---

Ọgbęni T. A. Ęrinoșo ję Ojulowo Onișowo. O nfi ọja ransę, o nta ọja, o si nra ọja, o ję Onișowo pataki ninu Ękurọ Epo, ati orișirisi Ọja miran. Ọgbęni na si tun ję ęniti o gba iwe ati ma ta Ilę, Ile tabi Oko.

Ę lọ fi Ọja nyin fun u ni:—

19, Opopo Tinubu,

Tabi ki ę kowe si ni:—P.O. Box 242, EKO.

## J. C. VAUGHAN

e-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja ...sior" ni Ita Agarawu, ni onjruru awọn ohun ...un tita ni owo ọpọku-ọyọku.

...nişowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun ...ti di oni.

...RI AJANAKU ni OGBẸNI na jẹ ninu ...won o...owo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbaɔiogẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Işo lorişirişi, Kokorọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ...i No. 4, Idunmagbo Street, (I'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ f animọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

On si ni aşoju awọn ẹgbẹ Oyinbo onişowo ... njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n ...anchester (Ni'lu Oyinbo) to si nranşẹ ...i-rişi ọja fun-ni lat'ọdọ wọn ni Eko ati ...egbe rẹ. Lọ ş'abere ẹhin ọrọ nipa owo ...owọ rẹ ni Şabu rẹ tâbi ki o kọwe ranş... o fi şọwọ sinu apoti ikọwe si t'Ọbẹ P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.

## Ẹ WA WO O.

Ọgbẹni E. A. Olemọh ti Ile Işẹ Oluwa, ni 73, Ọdunfa Street, (Anikantamọ) bẹrẹ işẹ agbọrun titunşe ti baba rẹ nisisiyi. Ojo eşe ti iwọ ati obinrin rẹ ma nsaba ju agborun ...uyin ti o ba bajẹ nu, Kai! Ọgbẹni ...an mbẹ ni adugbo mi ti o mọ şẹ agb...orun ni...e l... ...lowo rẹ.

## ŞABU AJIŞEFINNI.

Gbakan-nşubu orişirişi Ọti *Beer* to jire wa fun tita ni Şabu Ibukun Oluwa, Şabu ti Mrs. A. Labinjọ ni No. 28, *Luther Street*, leti Mọşalaşi Olosun. Sarotu kekeke (*Cigarettes*) si nbẹ nibẹ bi tẹdi. Awọn *Lozenges* ati *Peppermint* lila, papa lakoko oworẹ yi ko şe fọworọ sẹhin. Gbogbo awọn ọja Şabu na lo nşẹju si ni, pe kami, kami, kami.

Ọrẹ, sure tete lọ ra tirẹ nibẹ.

Kai! afara ni'ja Ẹkun.

Cable Address:—

"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**

**HAMBURG, Neurwall 16|18.**

**Hildebrandhaus.**

*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for

English and Continental Goods

and

PRODUCE

Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—

**Mr. Karimu Kotun**

3, DOSUNMU STREET.

**Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from:—

DURO THOMAS,

55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**



THE

# Pilsener Beer

*Lion Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**34s.**



## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trade,*

has on hand Woollens in endless v... at 50, Dosunmu Street, Lag...

***Prices to suit everybo...***

*Call now, fortune awaits yo...*


ILU EPE KO KERE L'AWO, EIYE O... LO GE.

Ogbeni S. A. O. Macaulay ti No. 88 l'Eko nibi sese si Ile Egbogi to keriri kan si eti Ebute l'Epe.

Ile Egbogi na ko jina si Ile-Oja awon Oyinbo Onisowo John Holt.

Ogbeni yi ni Ajalolẹru Egbogi ni Sabu... na, eyiti ki foju arunkarun ba'lẹ gẹrre ti a... ba ti lo wọn.

Ẹ wa dan a wo; bẹ lẹ o ba.

Ọpọku-ọyọku ni owo tita wọn.


## B. A. OLA SILVA,

**Certificated Typewriter Mechanic**

*5 years Mechanical experience Marine Work Shop...*

Undertakes Repairs of Typewriters, &c., ... moderate charges.

*Business Place:*

30, DOHERTY STREET, LAGOS.

**A Trial Solicited.**


## Ile Ita Egbogi ti Macaula...

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orisirisi Egbogi lo sẹsẹ ... wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orisi... ogun Ẹda, ogun arun asiri, ogun Arẹmo, ogun Onigbameji, ogun Aran orisirisi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mâ to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si je bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREE... EKO ... PUBLISH...